# IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE, TENI GBOGBO LAWA

No. 727 WEDENSDAY, JUNE 24, 1964


## Ijọba Da Awọn Oṣiṣẹ Mejileladọta Duro

ILỌRIN:— Ibanujẹ dori agba kodo ni irohin to kan gbogbo awọn oṣiṣẹ Ijọba Ibilẹ Ilọrin ni deede agogo mẹjọ kutukutu owurọ ana ọjọ Aje ti iṣe jọ keji lelogun oṣu yi nigbati awọn alaṣẹ Ijọba Ibilẹ Ilọrin fun awọn oṣiṣẹ mejileladọta ni iwe idaduro patapata kuro lẹnu iṣẹ.

Ninu awọn oṣiṣẹ ti Ijọba daduro wọnyi ni awọn alagbẹdẹ, gbẹnagbẹna ati awọn ọmọlẹ. Ọkan ninu awọn agbọrọsọ Ijọba Ibilẹ na sọ fun oniwe irohin wa pe, eyi ni igba keji ti Ijọba Ibilẹ na yio da enia duro lẹnu iṣẹ wọn.

Siwaju si i, agbọrọsọ Ijọba na sọ pe ohun to fa ti Ijọba fi da awọn oṣiṣẹ duro ni ọda-owo ti o da Ijọba lati ibẹrẹ dun yi ni apo Ijọba ti ṣebi ongbẹ, ti owo-oṣu awọn oṣiṣẹ si di ṣegeṣege ti nwọn ko si nri owo-oṣu wọn gba deede nipa ọda-owo to da Ijọba na. Nitori idi eyi ni Ijọba ṣe da mejile ni adọta enia duro ninu awọn oṣiṣẹ na.

Ọkan ninu awọn oṣiṣẹ mejile-ladọta ti Ijọba da duro na ṣe alaye fun oniwe irohin wa pe, o ti le ni odun mejila ti on ti nṣe iṣẹ labẹ Ijoba Ibilẹ Ilorin on ni iyawo meji nile on si ni omo mẹsan nile awon meje lo si nlo si ile iwe ninu awon omo na.

Pẹlu omi oju ni okunrin na fi rojo fun oniwe irohin wa. Ṣugbon ni ipari oro rẹ o ṣe alaye siwaju pe oro idaduro na jẹ kayefi fun on.

Gbogbo awon oṣiṣẹ na ṣe ipade ke kere kan lana nwọn si ṣe ipinnu pe gbogbo awon yio lo ri Ajẹlẹ Ilorin ni owuro yi. Bi Ajẹ lẹ Ilorin ba ti pari oro na si ọo si ma a gbo.

## Adajọ Agba Ipinlẹ Ila Orun Naijiria Ti De S'Eko

# IJỌBA FẸ ṢE IDAJỌ ẸJỌ AWOLỌWỌ L'ỌLA BI?

EKO:- Irohin ti gbogikan kakiri gbogbo agbaiye pe ninu ọsẹ ti a wa ninu rẹ yi ni Ile ẹjọ giga julọ fun Orilẹ-ede Naijiria yio ṣe idajọ ẹjọ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, olori ẹgbẹ Afẹnifẹre ati awọn enia mejila miran pẹlu rẹ ti Apapọ Ijọba Naijiria mba ṣejọ iditẹ si Ijọba ati igbiyanju lati doju Ijọba bolẹ ati ifi ipa ko awọn ohun ọsẹ wọlu.

Gẹgẹbi irohin ti a ri gbọ ni owurọ ana, Ile ẹjọ gigajulọ na ko kọ awọn ẹjọ ti o wa niwaju wọn lati da ninu ọsẹ yi si ara patako akiyesi gẹgẹbi nwọn ti nṣe lati ẹhin wa. Eyi si fi han gbangba pe, nwọn fẹ ṣe idajọ na ti yio fi je wipe, gbogbo enia ko ni le gbo titi ti nwọn o fi da ẹjọ na.

Ṣugbọn ki idajọ na le ba gbogbo enia ni ojiji ati laiko ro tẹlẹ.

Onirohin wa kan fi ye wa pe, Ọlọla Louis Mbanefo, Olori gbogbo awọn adajọ Ipinlẹ Ila Orun Naijiria ti nwọn jijọ gbọ ẹjọ na ti de si Eko, ni ibẹrẹ Ọsẹ yi.

Onirohin wa na fi ye wa pe nitori idajọ ẹjọ Oloye Awolọwọ ni adajọ na ṣe wa si Eko iṣe ọjọ keji oṣu ti mbọ na yi, ni Ile ẹjọ na yio mu ipade ijoko wọn ti asiko yi de opin titi di oṣu kejọ ọdun yi.



OLOYE ỌBAFẸMI AWOLỌWỌ

Onirohin wa kan fi ye wa pe, gbogbo awọn adajọ mararun ni wọn ṣe ipade ninu ile ẹjọ na ni owurọ ana.

A si lero pe ohun ti nwọn ṣe ipade na le lori ni lori ọran idajọ ẹjọ Oloye Awolọwọ. Nigbati o di deede agogo meji ọsan ana ni nwọn pari ipade na.

Gẹgẹbi irohin abẹlẹ ti a ngbọ, a gbọ wipe, "Ile ẹjọ na yio se idajọ ẹjọ oloye Awolọwọ ni ọla tabi ni ọtunla, ṣugbọn ẹnikẹni ko ni gbo titi di ọjọ idajọ na"

Awọn adajọ na ni, ọlọla Adetokunbọ Ademọla olori gbogbo awọn adajọ fun Apapọ Ijọba Naijiria, Ọlọla Louis Mbanefo, olori gbogbo awọn adajọ ni Ipinlẹ Ila Orun Naijiria, ẹniti o de si Eko ni opin ọsẹ yi, Ọlọla Lionel Brett, Ọlọla Vahe Bairaman ati Ọlọla J. I. C Taylor.

### "AWO"

Oniwe irohin kan fi ye wa ni ana pe, Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ko ni wa si ile ẹjọ na ni ọjọ ti nwọn o ba ṣe idajọ ẹjọ rẹ, ṣugbọn a gbọ wipe awọn alaṣẹ Ọgba awọn ẹwọn sọfun pe, "ki o ma a palẹ ẹru rẹ mọ, ki o si i ma a mura sile diẹ diẹ "Ojo ti o rọ lana ko jẹ ki oniwe irohin wa o le

WO OJU EWE KẸFA

Ṣugbọn Onirohin ti o wa adajọ na lọ si ile lana ko ba nile nitori Ojo ti o ro lana

Ọkan ninu awọn Alaṣẹ ile ẹjọ na ṣe alaye fun Oniwe irohin wa lana pe, Ọlọla Adetokunbọ Ademọla yio gba isimi ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi,

Bakanna ẹwẹ, ni Ọlọla Vahe Bairaman yio gba isinmi tirẹ na ni ọjọ kẹta oṣu ti mbọ yi ati Ọlọla Lionel Brett yio gba isimi tirẹ na ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu yi.

Irohin na tun fi ye wa pe ni ọjọ ọjọ'Bọ ti



Lateef Jakande



Ọlọla Ade. Ademọla



Ọgbẹni Kellock



Ọgbẹni Ọdẹsanya

# ITAN IGBESIAIYE OLOGBE ẸNIỌWỌ TẸLA

Igi nla ki wo ninu igbo ki awọn ẹiyẹ ti o kọ ite wọ le lori ma mọ. Bẹ ni awọn ẹranko ti o nje labẹ igi na ko le salai mọ rara. Bi eyi o to wipe ti omi ba sigbẹ gbogbo enia to npọnmi rẹni lati mọ lara pupọ. Nitorina bakanna ni bọ Ologbe wa Rev. R.A.D. Tẹlla olohun iyọ ti ijọ Ebenezer Baptist ni Eko.

Laisi aniani igi nla wo nigboro Eko. Nigun mẹrin Eko ko si ibi ti ako mọ baba wa yi fun nkan pataki wọn yi. Baba ẹni ọwọ yi jẹ onisẹ rere

Ninu awọn to mọ ilo Yoruba baba yi jẹ asiwaju ninu ede Yoruba Ti o ba wa lori pepele iwasu awọn ti o jẹ olorun ko ni le sun

Ẹniti o si sun yio taji giri ati laju fun alaye ọrọ Ọlọrun. Ẹni ọwọ yi jẹ ẹniti o bẹru Ọlọrun pupọ Ki ṣe onigberaga rara

Ọlọrun fun niagbara ati imọ bi oti sele ko enia jọ ati lati ko wọn je ni ọna ti ko ni si inira fun awọn ti o wa ni arọwọto rẹ,

Ẹni ọwọ yi mọ ọna ati gba nkan lọwọ enikẹni laisi inira Eyi ni pe ki fi ipa gba nkan to je ẹtọ rẹ lọwọ ẹnikẹni Osi jẹ onilara ododo

Ṣugbọn pẹlu ọrọir lẹ ati iwa jẹjẹ ni ẹni owọ yi fi ma tọ ni si ọna ati tẹle ọna ododo nipa eyiti ẹni na yio fi ri isina rẹ. Baba wa yi ki ṣe ẹniti ma hale rara.

Awọn opitan sọ fun wa pe abi ẹni ọwọ na ni ọjọ kẹtala osu March 1870 ni Ilu Ọba nla Yoruba ti ise Ọyọ. Gẹgẹbi awọn ọmọde ti nkọ ẹkọ wọn ni on papa na lọ si ile-iwe ni Christ-Chruch Faji ni Eko

Lẹhin igba diẹ o tun lọ si ile iwe ni First Baptist

Fun idi eyi ni Alagba J W Vaughan ati Rev M L Store yan lati ri aye silẹ lati ma kọ Ologbe Rev Tẹlla ni ọna Ẹkọ Bibeli (Theology)

Lẹhin ti baba wa jina ninu ẹkọ ti nwon ṣe fun u. Bi o ti ntẹ siwaju ninu ẹmi, bẹni o tun ya bara fun nkan bi ọdun mẹta lati lọ ṣe iṣẹ akọwe ni Reluwe

Gẹgẹ bi ẹniti Ọlọrun ba fẹ lo fun iṣẹ Rẹ yio ni lati pe pada fun iṣẹ Na.

## (ONIWASU)

Nitori o di ọdun 1904 baba yi bẹrẹ iṣẹ olukọni ati oniwaṣu kekere ni Agege ati agbegbe rẹ.

Bi o ti nkọni ni ilewe bẹni on papa tun gba ẹkọ Ijinlẹ lati ọdọ Rev. M L. Stone ẹniti o jẹ onimimọ julọ ninu ọrọ Ọlọrun ni asiko tirẹ.

Lasiko yi ni gbogbo igboro Eko. ko si oniwasu to le fi ọbẹ iwasu Rev. M L. Stone jẹun. Eyi ni pe, gbogbo awọn oniwasu ma wari fun agbara Ẹmi to nlo Alufa yi-M.L Stone.

Lẹhinti baba wa Ologbe jina ninu ẹkọ Iwasu ni abẹ Rev M. L. Stone ran lọ jade si Ijero Baptist Church, Ebute Mẹta g gẹ bi bi asaju Ijọ na, O ṣe e y i un ọdun kan. Bayi o ju wa s ọ ọ si lara pe o to gba fun, oye alufa kikun,

Nigbati o di ọjọ kẹtala oṣu March 1921 ti iṣe ayajọ ibi rẹ ni a wa pe si ipo oye kikun fun iṣẹ Ọlọrun, Lehin ti on je ọmọ ọdun mẹtalelogoji,

O dabi ẹnipe baba yi ati ọjọ ibi rẹ lo nṣe iṣe pọ, Eyi ni ama ori ire kan pataki fun Rev, Tella nipa wipe Rev. Samuel George Pinnock gbe ọwọ o y e kikun le Rev, Tella ni ọjọ kẹtala oṣu March 1921

### EBUTE-MẸTTA

Lẹhin ti baba wa kuro ni Ijero Baptist Church, Ebute-Metta o tun ṣe iṣẹ fun ọdun meji ni Jehovah Jire Baptist Church, Ebutte-Metta.

Lẹhin n a o ṣe iṣẹ ni Union Baptist Church Eko, Lẹhin ọdun pupọ t i o ṣe iṣẹ Ọlọrun kiri o w a ṣẹṣẹ pada w a ile rẹ owurọ to fun n i imọ Ẹkọ Ọlọrun,

### IṢẸ IKẸPỌ

Eyi ni Ijọ Ebenezer Baptist Church ti o je ijọ Deacor J. W. Vaughan ẹniti o j ẹ opo nla kan fun Ijọ na. Lati igbana (1937) ni baba wa yi fi wa larin ijọ Ebenezer Baptis' Church.

Laisi aniani l a t i igbati Ẹ n i ọwọ yi ti wa ninu Ijọ yi, a ko gbọ wipe edẹaiyede dide lati ọwọ rẹ tabi lati ẹnikan.

Eyi fi han p e Ọlọrun ln yan a fun Iṣẹ rẹ. Ami to han si n i gbangba ni p e irẹpọ ifi ọwọsowọ ṣiṣẹ wa larin Ijọ yi, Nitori na, Ibi ti Ẹmi Ọlọrun ba nṣiṣẹ irẹ p ọ ayọ n i o manwa ni nbẹ ko si ibi t i kikun ki wa bi kikun ba w a n bikibi a jẹ wipe kikun ti ifei fun iṣẹ Ọlorun, Larin awọn ọmọ ẹhin Jesu papa gidi Maria kun s i arabinrin re wipe Oluwa eṣe ti o k o fi sọ fun arabinrin k i o w a ran mi lọwọ? Bayi n i ọrọ Ọlọrun nṣe iṣẹ,

### NIGBAGBỌ

Laiṣi iwa agabagebe a le s ọ npati Rev, Tẹlla pe didun ni iranti baba wa yi Eniti o sun ninu Oluwa ti o si ma tasi waju nigbagbo

Nje ha le gbagbe ohun kẹlẹ ohun irẹlẹ to la idi ọrọ Ọlọrun yeni jakejado ilu Eko yi. Ohun rere kan wa nipa Rev R A D Tella

Eyi nipe ẹkọ iwa irẹlẹ to fun awọn ọmọ rẹ ẹkọ nipa imọ Ọlọrun to fun wọn yiti wọn ndagba ninu awọn ẹkọ imọ Ọlọrun lojojumọ

Laisi aniani ibukun nla leyi A le wi eyi ipa Rev



OLOGBE ẸNI—ỌWỌ R. A. D. TẸLLA
Alufa Ijọ Ebenezer Baptist Church



Ọgbẹni S. O. Jaiye

Ah! Tella nibo ni ohun rẹ wọnyi wa?
Ohun ifẹ, ohun ayọ ti iṣe alore Jesu
Wa, Ebeuezer sọkan fun ọwọ rẹ to lọ,
Sile aiyeraiye loke ibi islmi ẹni mimọ

Mo ni sọk n apohun rere ẹkun idagbere rẹ
Fun ahọn to wasu ọrọ NA fun aiye gbọ,
Wa, pada wa, Ẹni ọww Tella baba ọwọn,
Lati jẹ iṣe rere rẹ larin agutan rẹ

Ye! baba ọwọn iru irin ẹsẹ rẹ jẹjẹ ni
Ti Ijọ rẹ fẹ larin wọn yo ha dopin bi?
Larin ọmọ enia bi bẹ ẹ ni ipo rẹ da?
Yo ha sofo titi aiyeraiye naọjọ ikẹhin

Ẹ ku aṣẹhinde Ebenezer Ijọ Ọlọrun,
Ipo baba to sọrọ yo din larin nyin
Bi adura ẹbẹ ba wa larin Ijọ rẹ,
Fun itọni ati imulọkanlẹ ninu Ẹmi

Odigba o ṣe Rev,Tẹlla
Ẹni ọwọ tun ara wa ri
Nigba ipe ikẹhin yo dun
Fun awọn tirẹ, odi arọ o.

# IWE SI OLOTU

## Ẹrọ-Asọrọmagbesi Fi Iya Jẹ mi !

Lọjọ kẹwa oṣu June nigba ti gbogbo awọn oṣiṣẹ binu da iṣẹ silẹ nitori ẹkunwo, lati igba ti a si bẹrẹ idaduro iṣẹ na ako ri owo gba ebi si npa wa.

Ṣugbọn nigbati agbọ ninu ẹrọ Asọrọ-Magbesi pe diẹ ninu awọn oṣiṣẹ Port Authority ati awọn ọmọ Biney ti pada si ẹnu iṣẹ inu mi dun, nitoripe emi jẹ ọkan ninu awọn oṣiṣẹ Port Anthority

Ni 11th oṣu June lọjọ keji mo lọ si Apapa nibi iṣẹ wa mo si wọ ibi iṣẹ wa lọ, apo asi to ọgọrun enia to lọ si ibi iṣẹ ri ọjọ na

Bẹni awọn ọlọpa ati ṣọja de, nwọn ko pompo tiwa, nwọn si luwa tẹrun, soja kan fi idi ibọn jlom ni igba aya ọlọpa kan fi pompo kan mi ni ẹrẹri, ẹjẹ yọ. ọna odi ni mo ba dele, eyi ṣẹlẹ ni ọjọ 11/6/64

Eyi fi mi laiya balẹ pe nkonigba ọrẹ Asọrọ magbesi gbọ ni ọjọ miran mọ.

Emi ni,
Idowu James
Apapa

yi, tabi Ọgbẹni Ọlabimtan ni ko ko wa mọ ni, ẹ ba wa sọ fun Ọgbẹni Afolabi Ọlabimtan pe a nfẹ itan Ifẹloju ni klakia.

Ẹ ku iṣẹ O.

Emi ni,
EKO. Falilatu Arẹago

## A Nfẹ Iwe Irohin Imọlẹ

Olotu, Inu mi yio dun bi ẹnyin pẹlu awọn oṣiṣẹ yin ba le ṣe iranlọwọ fun wa gẹgẹbi ao ṣe ma ri iwe yin Oloyin mọmọ 'Irohin Imọlẹ' ka ni ilu Ọwọ nigbagbogbo.

Iwe na si jẹ ohun to fa ọgbọn yọ fun awọn ọmọ ile ẹkọ, ati papa awọn itan orişirişi to ma a nwa ninu iwe yin. Eyi ti iwe yin na ti de Ọwọ to oṣu mẹrin sẹhin a ko mọ ohun to fa ti a o fi ri iwe na mọ. Inu wa yio dun pupọ oi ẹ ba le jẹki iwe na ma de Ọwọ wa nigbagbogbo yio dun mọ wa lọkan pupọ

Awa ara ilu Ọwọ ti rope boya iwe na ko wa laiye mọ nigbati a ko ri iwe na mọ awa ara ilu Ọwọ si ni ọkan pe iwe na yio to wa lọwọ laipẹ yi ati pe awa nfẹ ma gbo ọrọ Yẹyẹnatu Oniyẹyẹ Eko ninu iwe na A nreti yin o Olotu.

Emi ni,
Anthony Adẹọla
ỌWỌ.

## Itan Ifẹloju Nko?

O ti nlọ bi ọdun kan sẹhin ti a ti ma ngbadun itan IFẸLOJU eyi ti Ọgbẹni Ọlabimtan nkọ sinu iwe Irohin Imọlẹ, ti gbogbo awa Onkawe na si ngbadun itan na, nitori itan yi kun fun ọgbọn ati ọpọlọpọ oye o si tun kọ nipa ifẹ otitọ, larin ọkọ ati aya, şugbọn lati ibẹrẹ ọdun yi a ko ri itan na ka mọ, bẹsi ni itan yi ko ti tan.

Ni idi eyi, mo fẹ ki Olotu sọ fun wa ohun ti ko jẹki a ri itan na ka mọ nigbati ki iṣe pe itan na ti tan, nitori mo ranti pe apa kejidinlogun ni ẹ ti da itan na duro ni ọdun to kọja.

A bẹ Olotu, ki o ba wa tun bere itan na lati tun ibẹrẹ itan

## Ọlọrunjare Nfẹ Atunse

Olotu ẹ jọwọ ẹgba mi ni aye ranpẹ ninu iwe nyin Ojojumọ lati ke si awọn ọmọ ilu Ọlọrunjare to wa nile ati loko lati jẹ ki a mura si ilọsiwaju ilu wa ni asiko ti gbogbo enia nsowọpọ fun ati tun ilu wọn ṣe. Ẹjẹ ki awọn Ọkunrin tun okun soko wọn so ki awọn Obinrin si tun okun tobi wọn se daada.

Bi a ba le ran arawa lọwọ nigbana ni ato le kesi Ijọba Ipinlẹ Ariwa yio wa to ran wa lọwọ, Owe Oyinbo kan sọ pe, ẹniti o ba ran arare lọwọ ni awọn ogun Orun ran lọwọ. Otitọ ni owe na.

Asi nfẹ ki Ijọba Ipinlẹ Ariwa mọ wipe bi ilu kan ko ba dara ninu Ipinlẹ Ariwa gbogbo ipinlẹ Ariwa ni ọkan laiku ilu kan, nitoripe ẹtẹ awo na ni ẹtẹ ọgbẹri.

Gbogbo awọn ilu kan ti ko tobi to ilu wa ẹnyin ijọba rere na ntunse, afi ilu wa nikan ni ẹdasi ẹjọwọ, ẹ ṣanu wa, ki awọn ọmọ wa na le mọ fi ilu ti wa na yangan.

Olotu iwaju ni ọpa ẹhiti nyin yio ma re si amin ati amin.

Emi ni,
Ọlọrunjare. A. Sunmọnu

## E Ran Wa Lọwọ O Ọlopa

Olotu inu mi yio dun bi ẹ ba le gba mi ni aye ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi awọn Ọlọpa ilu Ibadan lati ran wa lọwọ nipa awọn ọlọṣa ti ko jẹ ki awọn onile sun to ba ti di oru ọganjọ tabi ti awọn ẹhanna ọlọṣa yi ba ti mọ pe ko si onile nile nwọn yio si fọ ile na nwọn si sọ onile na di talaka patapata.

Ibi ti awọn nkan wọnyi ti nṣẹlẹ pupọ ni Fọkọ, Bẹrẹ ati Oke-Arẹ inu awa ti ngbe awọn adugbo wọnyi yio dun bi awọn ọlọpa ba le ṣe iranlọwọ na fun wa lati ba wa ma bojuto iwa awọn fọlẹfọle wọnyi ati pa pa julọ ti ọsan ti awọn enia yio ti lọ si'bi iṣẹ wọn ti awọn ọlọṣa y'o wa sọ ile wọn di ahoro. A nreti yin o Ọlọpa. Modupẹ pupọ o Olotu.

Emi ni,
Ademọla Ashimi
IBADAN.


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* M O D U P E P R E S S
*Because Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHODS OF PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*

Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.



## Awon Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ Etutu sise iwosan ati egbogi ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku ko ni yọọ lẹnu mọ oso ati ajẹ ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ọ ohunkohun ti oba si dawọle rere ni yio ja si awọn babalawo ti o ngbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri ọ mọ, iye owo 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbabiẹtu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko ṣe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ ṣaṣa ni arun ti o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arunkarun tabi asasi kan le pa ọ mọ. Iye owo 25/-

Turari Ẹyọnu Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti ṣe ṣalaye rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohunkohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwe ko ti mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo yio si wa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| PaKngolo kan | 10/6d |
| Iekere | 2/6d |
| we Gbedegbẹyọ Hausa | 3/- |
| Itumọ JosẹfuAlala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ile Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọṣẹ Iṣẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| Lilo ati agbara Psalm Iṣẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Turari | 30/- |

## APEJUWE ILE IṢẸ WA

Wọ Bọọsi ti o nlọ si Lawanson ni Yaba 3d pere ni, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti o ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ibẹ ni ile itawe wa wa Ti o ba fẹ fi owo ranṣẹ fun ọja ẹ A dirẹsi mi niyi:—

**J. O. Shoyinka**
c/o Postal Agent
1, Isiba Street,
Itirẹ Via,
Suru Lere, Yaba

Akiyesi Pataki:- ale ri awọn iwe wọn yi ra ni garaji ddo, Mushin, Ikorodu road ati gbogbo ile itaja iwe Ti o ko ba ri i ra wa si ọdọ mi ngo ta fun.

# Ọdaran Kan Fi Ipa Ba Obinrin Lopọ

IJẸBU-ODE:- Ni ọjọ Aiku ti iṣe kẹsan oṣu yi ni adajọ ile ẹjọ giga ibilẹ ti Ijẹbu Ode ju Ọdaran Ọkunrin kan. Oluṣọla Adekọya ẹniti apele rẹ njẹ "Tiger Pedro" lọ si ẹwọn ọdun mẹrin pẹlu iṣẹ iṣẹ aṣekara fun ẹsun pe o ba Obinrin lopọ pẹlu ipa

Gẹgẹbi ọrọ agbẹjọro ni, ni ile ẹjọ na pe Oluṣọla Adekọya fi tipatipa ba ọmọ binrin kan lopọ ni adugbo Oyingbo, Ijẹbu Ode.

Agbẹjọro fi ye ile ẹjọ pe nwọn ran Ọga awọn Ọlọpa kan lọ lati lọ mọ Ọdaran na ṣugbọn o kọ dele fun Ọlọpa na lati mu on lọ.

AGBARA DIN KU

Lẹhin ti ọga ọlọpa to lọ lati lọ mu ọdaran na Ọga awọn Ọlọpa agba ọgbẹni Yisa Lawani si fun ara rẹ lọ lati lọ mu ọdara na. Ọdaran na si bẹrẹ si ṣa agbara titi pẹlu ọga ọlọpa na ṣugbọn ni ikẹhin agbara rẹ si dinku to jẹ pe ọ ọlọpa na si mu lọ.

Adajọ ile ẹjọ na ọgbẹni Abiọdun Oguntoye sọ ninu idajọ rẹ pe eleyi jẹ ohun iyalẹnu fun on lati ri pe Adekọya ko ti fi iwa jan duku silẹ lati ma daamu awọn obinrin larin igboro.

Ninu ọrọ ẹbẹ rẹ niwaju adajọ pe koṣe anu on pe on ṣe ileri pe on ko ṣe bẹ mọ ati pe on si ti kọ iwa buburu na silẹ.

# Yẹ Irawọ Rẹ Wo

AQUARIUS (Jan 21 - Feb 18) Ṣọra loni ki o ma ba ṣamodi. Edeaiyede yio gbilẹ ninu ọrọ kan ti ẹnkini ko ni gba fun ẹnikeji, gbidanwo lati fi ara lelẹ fun igba diẹ. Maṣe fi ọkan balẹ si iranlọwọ enia, ma a ṣiṣẹ niṣo bi iṣẹ rẹ ba da ọ loju.

PISCES (Feb 19 - Mar 20) Ṣe ipinnu lati ṣiṣẹ, iwọ yio si nitẹlọrun. Ṣọra ki o maṣe fẹnu sọ ohun ti yio pa ọ Maṣe ṣe nkan lainidi tabi ju bi agbara rẹ ti lọ mọ, o tọ ki o lọ si mi diẹ.

ARIES (Mar 21 - April 20) Awọn irawọ rẹ ti gbana soju, nṣe ni nwọn o ma wa ija. ṣọra rẹ ki o maṣe si arẹ.

TAURUS (April 21 - May 20) Ọrọ awọn ẹbi rẹ yio mu ọ jagbọn tobẹ ti iwọ yio ri aye lati tẹ siwaju, Bi ọrọ rẹ ba si lodi si ti alatako rẹ, maṣe jẹ kigbọ, kigba

GEMINI (May 21 - June 21) Bi o ba jẹ wipe ọrọ irin ajo de si ọ, ṣọra ki ọkọ re ma ṣe jamba. Ifọkanbalẹ rẹ. ewu nla li o jẹ, kosi ṣọra rẹ nipa isowọ si lopo rẹ pẹlu awọn ẹlomiran. Maṣe ja, bi ibinu ba goke, ṣa ṣe jẹjẹ.

CANCER (June 22 - July 22) Ohun ti o nro lọkan rẹ le gbẹhin si ofo tabi aṣiṣe. Maṣe ṣe ohun kan lai kọkọ fi si ero, ijọngbọn kekere kan yio bẹ silẹ nitoripe o yẹ ki o gba imọran lati ọdọ ẹlomiran.

LEO (July23- Aug23) Ọjọ oni ṣoro jọjọ, tun ọna rẹ ṣe ni iru ọna ti o ma ngba ṣọ nkan, bi iwọ ko ba fẹ idina, maṣe jẹki igba bọ lọwọ rẹ, ṣọra.

VIRGO (Aug 24 - Sept 23) Iṣọra wa fun ọ loni rẹpẹtẹ, maṣe ni inu buruku bi bẹkọ iwọ yio ba ajumọṣe rẹ pẹlu ẹlomiran jẹ, iwa jẹjẹ ati suru nikan lo le ko ọ yọ, lọ farapamọ si ibiti o ba ṣe kọlọfin.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Oyẹ ki o bẹru ijọgbọn ṣiro gẹgẹbi o ti nnawo si. maṣe jẹki ẹnikan ṣi ọ lọna, laju rẹ silẹ ki o wo iru ọna ti o fi mba awọn enia lo, ṣọra ki o maṣe atalo si si ọrọ ẹlomiran

SCORPIO (Oct 24-22) Mu ileri rẹ ṣẹ, ki o ma ba lu ijọgbọn ọrọ ti o gbẹkẹle ko ti tobẹ. Maṣe fi oju tinrin imọran lati ọdọ ẹlomian wa ki o ma ba ba gbogbo rẹ jẹ mu ara rẹ dan ki o si ni suru.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Ṣọra nitoripe gbogbo nkan ko le ma lọ deedee gẹgẹbi o ti nfẹ ki o ri. Maṣe jẹ ki amodi rẹ gbe ọ ṣanlẹ depo ti yio sọ ọ di olori buruku, oku Ọrun ko ninu didun si o pẹlu.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 20) Maṣe jẹki ọrọ tete ma jade lẹnu rẹ, maṣiṣe nireti owo nla kan, ki o ma ba mulẹ mofo, Toju ailera rẹ maṣe fara silẹ.


# Iwọ Ha Fẹ Kọ Ile Bi ?

Bi o ba fẹ ra ilẹ tabi o fẹ ta ilẹ tabi boya o fẹ kọ ile.

Tete kọwe si wa fun gbogbo awọn ohun ti o ba nfẹ.

Bi o ba kọ ile, a le ma a ba ọ gba owo lọwọ awọn olugbe ile rẹ kia kia, kia owo na o si tẹ ọ lọwọ ni asiko.

Tabi ti enia ba je ọ lowo ti ko san, kọwe si wa, were ni a o ba o gba a lọwọ rẹ

Fun ẹkunrẹrẹ alaye, kọwe siwa, ki o si dan wa wo lẹ ẹ kan ṣo ṣo a o si fi ohun gbogbo tẹ ọ lọrun

J.O. Shoyinka.
General Manager
1, Ishiba Street
Itirẹ—Yaba



AWỌN EGBOGI ATAMATASE PATAKI TI ODAJU LATI ILU JAMANI FUN ITỌJU ARUN ARA ATI OJU-DIDUN PẸLU EKINI:-

# SEDO — PAYAL



(IPARA BI ORI)

Jẹ ojulowo egbogi lati fi ṣe iwosan orisirisi arun awọn "ARA" gbogbo ti o ba mba enia ja lara tabi o de ara gẹgẹbi ọwọ ẹsẹ tabi ara hihun tabi didun nigbakugba Inarun tabi akọ Inarun, Ewo, Rorẹ kakiri oju, Ela lapa lapa Ara sisu Alefọ Ekusa lori ọmọde tabi agbalagba egbo ẹsẹ tabi Adaajina egbo ẹsẹ ati orisirisi awọn amodi tabi awọn arun ara omiran gbogbo.

BẸNA SI EGBOGI.

Dara pupọ julọ fun awọn ti amodi ti a darukọ wọn si oke iwe yi ba nyọ lẹnu nitoripe iṣẹ rẹ ni lati ma mu gbogbo awọn "kokoro" buruku gbogbo ti o ba wa ninu "ẸJẸ ARA" enia, san patapata a si ma ṣẹ iṣẹ ribiribi ninu "oju" enia pẹlu. Awọn ti oju wọn a ma "nsu" tabi wo baibai tabi ti wọn ko le riran daradara lati ọna jinijini tabi ti o bdai enipe nkankan wa afara si oju wọn yio bẹrẹ si riran Kedere

Bi o ba ti le gbiyanju lati ma lo egbogi Jamani yi dede fun igba diẹ alafia yio de si ọ ju gbogbo rẹ lọ egbogi Furunculosin yi a tun ma mu igbọuṣẹ wọrọ wọrọ wa fun awọn ti inu wọn bale tabi ti wọn ki rigbọnṣẹ dede lojojumọ tabi ti igbọnṣẹ wọn mn nle korokoro nipa bayi jẹdijẹdi a bẹrẹ si ma yọ wọn lẹnu bẹni o si dara fun lilo fun awọn onijẹdijẹdi pẹlu awọn egbogi meji yi yatọ si gbogbo awọn robirọbi ti wọn nta kakiri Ṣọbu ilu Eko ati igberikọ Bere wọn ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos.

Waterloo Medicine Stores
8 Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji
AdedunChemist 4 Wakewa Srteet Yaba
ATI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA
IBADAN

# Atotileto Ati Hadji Yaya Gba Adangba Lalejo

Eko :— Lenuloloyi ni Alhaji Amuda Konike Alhaji Sindiku Adangba de si Eko lati Ilorin Odo Olola Atotileto ni nwon si de si. ni 31 Adam Street o si g b a won lalejo tayo tayo o fi orisirisi onje adidun te won lorun.

Ni ojo keji ti nwon de nwon si lo se abemo Alhaji Yaya O. Salawu ni ile re, 1, Fakolujoh Street l'Eko

Alhadji Yaya s se won ni wabi-wosi alejo irohin ko to afojuba ni. Nwon si ti pada lo ilu won Adele ba ire o.

# Ikomo Omo Lawal Misaringindin

EKO:— Ni ojo Eti ti ise ojo kejila osu kefa odun yi ni Olorun fi omo okunrin lanti-lanti ta Ogbeni Abudu Fatai Lawal ati ayanfe aya re, Iyaafin Olurotimi Lawa lore ni odun Nwon si se ikomo omo na ni ile won 53, Ashogbon Street l'Eko, ni ojo keje ti nwon bi i.

Alhadji Imam Shomade ati ijo mosalasi re, Eru - Owa ni o si se akanse isin isomoloruko. Nwon s so o ni Mhd, Monsuru Adeto-kunbo Ayinla, E g b o n baba-baba o m o na ati baba - baba omo na, na wabiwasi owo f u n oke - Aimoye alabaseye ojo na. Aseye ojo ni busiya o le gongo. Ki Olorun se omo na ni olori ire o.

# Imoran Fun Ebi Alhadji Titun

Olotu, Inu mi yio dun, emi yio si yo sese bi o ba le gba mi laye die, ninu iwe Irohin Imole lati le ba awon Alhadji alafe ati awon ebi won so oro die. A dupe o.

Ayanfe Olorun ni o ma a nlo si Mekka iosin f u n Olorun. Olori ire si ni won Ki Olorun se gbogbo wa ni olori ire o. Bi Alhadji ba de ni Mekka, e m se jeki a mu loroyan mo lati ma a da aso ebi fun won lo mosalasi Jimo. Gbogbo wa ko ni a ni owo beba lowo lati le da aso na Olorun ko fe inira fun wa. Anbo oro ni a nso f u n omoluwadi o.

Alhadji Awaiyewasere

# Ikilo Ni Imam—Agba Ibrahim Nse

Lati Owo:— ALHADJI AWAIYEWASERE

Bi a ba ronu jinle a o si ri i pe, nkan pataki kan ki i sele laini idi Ikilo pataki ni Imam – Agba Liadi Ibrahim ati awon Imam Ratibi nse fun awa musulumi pe, ki a mase da aso moto-moto (egbe-jo-da). Nitoripe, ko dara Ki Olorun fun won ni emi gigun ati alafia o.

Ni opolopo igba ti a ba nse igbeyawo tabi ti a ba nse isinku, ni imale (ki i se musulumi tabi mumiini o) ma a nda aso egbe jo-du tabi aso ebi.

Asa yi lodi si esin Islam. Asa yi ki i si fi ni, ni okan hale Ika (fingers) ko dogba Olorun Oba awon oba ko si da awa omo enia bakan na

O da awa oro A n a b i Adam ju ara wa lo. Elo—miran gun Elomiran kun Elomiran sanra Elomiran were El o m i ran ni ooye ogbon ati laakaye Elomiran de, go, supo, o si ronmu Daani gan an ni o je Elomiran fere lati ma a sise Elomiran si ya ole Elomiran ni owo beba pipo lowo gegebi Alhadji Nuru Sule ati Ati Alhaji omo ba Abudu. Whaidi ati Hdd ja Limota (Ilaro Ya iyi. Elo.niran ko i ni owo lowo, Elomiran ni agbara Elomiran ko si ni agbara rara. E ko ri nkan bayi pe, a ko dara wa ko dogba. Awon omo ika wa ko do gba rara.

# Akiyesi

Enikeni ti o ba fe ra Iwe "I R O H I N IMOLE" ni ILORIN ati agbegbe re, yio ri ra lodo Asoju wa, Oloye Titus Balogun India nlsurance Co. Minista Quarter, ILORIN. Kobo meji (2D) pere ni nta a.

*OLOTU*

# Awon Oja Ajebidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin tite Etutu sise iwosan ati egbogi ajebidan ti o ba ni iwe yi lowo, ab ku ko ni yoo Iru mo oso ati aje ko ni lagbara lori re, owo o iapa ko ni wo o ohunkohun ti oba si dawole rere ni yio ja si awon baba-lawo ti o ngbowo gba aso lowo enia ko ni ri o mo, iye owo 20/-

Iwe egbogi ajebidan Agbahietu awon Ogun Ajebidan ti o wa ninu iwe yi ko se so a fi ti o ba ra i, ti o ba ni iwe yi lowo sasa ni aronti o ko ni le wo ko si ni ijaya pe arunkarun tabi asasi kan le pa o mo. Ive owo 25/-

Turari Eyonu Aje ti o ba afin turari yi ba a ti se salaye re Aje ati abatenije ko ni foju si o lara ohun kohun ti o ba si dawole rere ni yio maa ja si, iwe ko ni mo alta oja agbaaa ko si ni wo igba re idabobo yio si wa fun iwo ati awon ebi re.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| we Gbedegbeyo Hausa | 3/- |
| Itumo JosefuAlala | 5/- |
| Itumo Ami Ara | 3/- |
| Eewo ile Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afose Isedale Yoruba ati Psalm Ajebidan | 3/6 |
| Lilo ati agbara Psalm Iseguo l o r i awon Aje pelu Turari | 30/- |

**J. O. Shoyinka**
c/o Postal Agent
1, Isiba Street,
Itire Via,
Suru Lere, Yaba


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING

*Many Firms Patronise* M O D U P E P R E S S *Because Of Their;—*
MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE M E T H O D S
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs:—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

# Modupe Printing Press

**16, Bamgbose Street,**
Phone 21985, Lagos.

# IROHIN IMỌLẸ

MỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No, 727 WEDNESDAY JUNE 24, 1964 (2D)


## Ọdaran Kan Na Ọlọpa

IJẸBU-ODE:— Oloye Abiọdun Oguntoye, adajọ agba kotu Ijọba ibilẹ Ijẹbu Ode ṣe idajọ pe ki Ọdaran kan, Jimọh Abudu ti iṣe ọkan ninu awọn Ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kan ni Ago-Iwoye ilu ti ko jina si Ijẹbu-Ode pupọ lọ fi ogoji pọnun (£40) tauran si kotu tabi ki o lọ fi ẹwọn Oṣu mẹrin jura nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn Ọlọpa mu u wa si ile ẹjọ fun ni ọjọ Aje ti iṣe ọjọ kejilelogun Oṣu yi.

Ọlọpa to ba Ọdaran na ṣẹjọ dahun pe, edeaiyede kan ṣẹle laria ọja Oyingbo, Ijẹbu-Ode lẹsẹkẹsẹ ni Ọlọpa kan, Edward Ibidapọ sare wa lati pari ija na fun wọn ṣugbọn nigbati Ọlọpa na de ibẹ ti ọrọ rẹ ko si ba ti won mu ni Ọdaran na ba fun ni "Tanpe?" nigba mẹta, ni gbangba ibudo moto ọja Oyingbo ti ko ba si ero to pọ nibẹ Ọdaran na fẹ salọ.

Ṣugbọn lẹsẹkẹsẹ ni awọn enia sare de nwọn si gba Ọlọpa na silẹ lọwọ rẹ ṣugbọn Ọlọpa na ko gba ki nwọn pari ija na fun awọn, lẹsẹkẹsẹ ni Ọlọpa na ba mu Ọdaran na lọ si tesan, awọn Ọlọpa Ijẹbu-Ode ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kefa Oṣu yi.

Ninu ẹjọ ti Ọdaran na so lati fi gba ara rẹ kalẹ o ṣe alaye pe Ọkan ninu awọn aṣiwaju Oṣelu lo on ni Ago-Iwoye on mọ nipa ofin on ko si jẹ fi ọwọ pa Ida Ọba loju. Ọlọpa lo fi iya jẹmi laiko ṣẹ"

Ninu ẹjọ rẹ Oloye Abiọdun Oguntoye ṣe alaye pe iṣẹ ile ẹjọ ni lati ripe awọn Ọlọpa ko rekọja aye wọn bakanna ẹwẹ ni awọn ki yio gba fun Ọmọ ẹgbẹ Oṣelu kankan ni Ijẹbu-Ode lati ma na awọn Ọlọpa ni Ọba ṣẹ idajọ gẹgẹbi a ti wi ni oke iwe yi.

# Ijọba Fẹ Ṣe Idajọ Ẹjọ Awolọwọ L'ọla Bi ?



Ọgbẹni Durand

ri Oloye Awolọwọ lana, ṣugbọn alero pe yio lọ fi oju kan Oloye na ni owurọ yi,

Onirohin wa kan rau wa leti pe awọn Ọjọgbọn Oyinbo Ọmọ ilẹ Gẹẹsi meji ti nwọn gbona ninu iṣẹ Ofin ati awọn amofin Agbẹjọro Ọmọ Ilẹ wa meji ni nwọn ṣe ẹjọ kotẹmilọrun Oloye na nigbati o bẹrẹ ninu Oṣu kẹrin Ọdun yi.

Orukọ awọn Agbẹjọro na ni, Ọgbẹni Victor Durand. (Q. C.) Ọgbẹni Thomas O, Kellock. Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya ati Ọgbẹni Olu Ayọọla,

A gbọ wipe Ọgbẹni Victor Durand ati Kellock ko ni si nile ẹjọ ni Ọjọ ti nwọn o ba ṣe idajọ na nitoripe. nwọn ti pada lọ si ilu Oyinbo, Ṣugbọn Ọgbẹni M. A. Ọdẹsanya ati Ọgbẹni Olu Ayọọla yio wa sile ẹjọ ni Ọjọ idajọ na.

Ni opin ẹjọ na, adajọ fi enia mẹrin silẹ ninu wọn nwọn si ku mejila pẹlu Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ.

Orukọ awọn enia mẹrin na ni Ọgbẹni Josaiah Ọlawọyin, Ọgbẹni Ọladiran Lawanson, Ọgbẹni Ọlatunde Akamọ ati Oloye Taiwo Ọrẹdẹhin

Ninu awọn olujẹjọ na ti Ijọba fẹ ṣe idajọ wọn na ni Ọgbẹni Michael Omishade, Ayọ. Akinsanya, Lateef Jakande, Samuel Otubanjọ, Samuel Onitiri, Sebastian Umorẹn, Uzodima Nwaobiala, Sunday Ebiotoma, Morison Okotiẹ-Yesin, Gabby Shaṣọrẹ, Adeyiga Akinsanya, ati Simeon Oyeshile.



Ọgbẹni Omiṣade

Irohin fi ye wa pe, gbogbo wọn ni yio wa si Ile ẹjọ ni ọjọ idajọ, ṣugbọn Oloye Awolọwọ ko ni wa si ile ẹjọ na gẹgẹbi a ti ṣe wi siwaju iwe yi.

Awọn alaṣẹ Ile ẹjọ na ṣe alaye fun oniwe irohin kan pe, o ti da oju to ada pe ninu ọsẹ yi ni Ijọba yio ṣe idajọ ẹjọ na, nitoripe, "ohun gbogbo ti ṣetan." Ṣugbọn awọn adajọ ko ti sọ fun awọn.

Oniwe irohin wa Ejo'ngboro lọ si ọdọ Ọga awọn Ọlọpa ni owurọ ana ninu ile iṣẹ wọn, ṣugbọn Ọga Ọlọpa na sọ pe. on ko ti ri iwe lati Ile ẹjọ na lati sọ ọjọ ti nwọn o ṣe ẹjọ na, o ni ninu iwe irohin na ni on ti nri i ka.

Ọga Ọlọpa na tun ṣe alaye siwaju fun Ejongboro pe, bi nwọn o ba ṣe ẹjọ na Igbimọ yio kọ iwe si on, ki awọn le ba ṣe eto bi awọn ọlọpa yio ṣe ṣe iṣẹ wọn ni ọjọ na.

Bakanna ni onirohin wa tun lọ si ọdọ ọgbẹni M A. Ọdẹsanya ti o si tun lọ bere lọwọ rẹ, ohun ti o mọ nipa ọrọ ẹjọ na. Ṣugbọn ọgbẹni Ọdẹsanya ni on ko ti ri iwe gbalati Ile ẹjọ, ki o sọ ọjọ idajọ na fun on, ṣugbọn on lero pe ninu ọsẹ yi ni Ijọba yio ṣe ẹjọ na.

Oniwe irohin wa yio tun jade lọ ni owurọ yi lati tun ma a wadi ọrọ na siwaju. Bi a ba si ti gbọ okodoro ọrọ na si. A fẹ ki ẹ gba awa Oniwe irohin Imọlẹ gbọ pe gbogbo rẹ ni ẹ o ma a ri ka ninu iwe irohin Iṣẹ wa ni lati ma a sọ ohun ti nlọ larin ilu fun nyin ni gbogbo igba.



Ọgbẹni Onitiri


## AKIYESI PATAKI

Enikeni ti o ba fe lati ra Iwe Irohin Imọlẹ" ni Ibadan ati agbegbe rẹ yio ri ra lọdọ Asoju wa. Ọgbẹni Lateef Animashaun, 1 Ararọmi Street, Ibadan.

Kọbọ meji (2) pere ni a nta a.

OLOTU



Printed and Published by Mcoupẹ Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor:- TUNJI ADEỌSUN 45, Campbell Street Lagos 24/6/64